571/77
IBADAN

WEEKS 28&29
Kongi WK 28
2 11 18
WK 29
1 5 15
Asiko Bks Wk 28
1 13 14 32
WK 29
9 28 33 42
ROSS WK 28
21&38
WK 29
16&22

**Imọlẹ Owuro**

EṢIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

UNITY NAP
For 3 sure bankers for week 29 send N5 to E. O. Adeyemi c/o P. M. B. 5230 Ibadan. OR come to Imọlẹ Owurọ Office Ib.

**3, 40, 48 nap**

Independent Paper Vol. XV NO 784 FEBRURDAY JANUARY 5—FRIDAY FEBRUARY 11, 1977 10K. (KOBO MEWA)

# EGBON JI ỌMỌ ÀBURO RẸ GBÈ

ỌWỌ awọn Ọlọpa ilu Ibinni ni Ipinlẹ Bendel ti tẹ obinrin abilekọ kan l'ori ọrọ ọmọ kekere jojolo kan ti awọn kan wa ji gbe salọ ni iyẹwu iya rẹ.

Ọmọ ọjọ mọkanla pere ni nwọn pe ẹjẹ ọrun na. Ni ipari ọsẹ ti o kọja yi ni nwọn si ri ọmọ na nibi ti ẹni ti o ji i gbe, gbe e si ni adugbo Ọsayemwere nilu Ibinni gẹgẹ bi awọn Ọlọpa ti wi.

Awọn Ọlọpa ilu Ibinni sọ pe, ninu iyẹwu ni iya ọmọ na tẹ ọmọ rẹ si, ti o ni ki awọn ẹgbọn rẹ kekeke meji maa boju to o ki oun fi ti ile iṣẹ awọn onisẹ Lẹntiriki ti njẹ NEPA de.

Ṣugbọn nigba ti iya ọmọ na de ti ko ri ọmọ rẹ lori itẹ ti o tẹ ẹ si, ni o ba beere lọwọ awọn ọmọ meji tihin ti o fi ṣọle nipa ibi ti ọmọ na wa. Awọn ọmọ na l'o wa sọ fun un pe, Aunti rẹ ti njẹ bayibayi l'o wa gbe e lọ.

Gẹgẹ bi irohin awọn Ọlọpa ti wi, nwọn ni lẹsẹkẹsẹ ni obinrin na tọ Aunti rẹ na lọ; ṣugbọn Aunti na sọ pe, oun ko de ile rẹ debi ti oun yio gbe e ni ọmọ.

Nihin ni obinrin na ti fi gbajare bọnu tọ awọn Ọlọpa ilu Ibinni lọ pe, ina jo oun; ni awọn Ọtẹlẹmuyẹ ba kojubọ ọran na.

Irohin sọ pe ninu ifimufiinlẹ kiri ni awọn Ọlọpa ti ri ọmọ na ninu ile kan ni opopo Osayemwere nilu Ibinni, nibi ti nwọn gbe e pamọ si.

Bayi, awọn Ọlọpa ti gba obinrin abilekọ kan ti nwọn pe ni Aunti iya ọmọ na mu l'ori ọrọ yi. Iwadi awọn Ọlọpa ko ti i pari l'ori ọrọ na.



ỌGAGUN ADEKULE LAWAL
Gomina Ipinlẹ Eko

## Iwadi l'ori Adamu Orisa

IGBIMỌ ti Ijọba Ologun Eko yan lati wadi si iṣẹ kikọ ile Adamu Oriṣa si ilu Eko, yio maa ba iṣẹ rẹ lọ bi o tilẹ jẹ pe Adajọ ko tii dajọ lori ẹjọ ti Oloye I. S. Adewale pe lori rẹ.

Alaga Igbimọ na, Ọlọla Fatai Dabiri l'o sọ bẹ ninu ọsẹ yi nilu Eko. Ọgagun Mobọlaji Johnson ni Ijọba rẹ paṣẹ kikọ ile na, Ijọba Ọgagun Adekunle Lawal l'o paṣẹ iwadi na.

## Misitura Aduke Gbe Are Asiko De!

EYI ni lati kede fun gbogbo araiye pe, awo rẹkọọdu ti Arabinrin Gbajumọ alare Dundun ati Ṣẹkẹrẹ nni, Misitura Adukẹ (Eyi ti a ti ta yin l'obobo rẹ tẹlẹ) ti jade fun tita bayi.

Awo rekọọdu Misitura yi ti Nọnba rẹ jẹ OKLP 67, dun pupọ, o kọyọyọ, ilu Dundun ati Ṣẹkẹrẹ ti o dun i jo ṣelẹ sibẹ, bẹẹ ni orin agbọdunnu kun inu awo na dọba.

Ara akọle awọn orin inu awo na ni iwọnyi:-

OJU KINNI
1 Orin Egungun Ololu
2 Ẹgbẹ Oke—Odo
3 Iba Araiye
4 Ija Tatalọ pẹlu Alamu Agboluaje

OJU KEJI
1 Owọn Ounjẹ
2 Ẹgbẹ Onimọto Mọlete
3 Oore l'o pe
4 Ọrẹ meji
5 Abiye Ọmọ

Koṣeemani ni awo rẹkọọdu Misitura yi fun gbogbo ẹni ti o ba ni ifẹ si are Dundun ati Ṣẹkẹrẹ

Tete lọ beere tirẹ ni:



MISITURA ADUKẸ

OGO OLUWA KIITAN TRADING COMPANY.
128, Agege Motor Road,
Atẹwọlara, Muṣin
Telephone 46252

Tabi ni ẹka wọnyi:
- 51 Railway Line Odi Olowo, Muṣin.
- 119, Herbert Macauley St; Ebutemẹta.
- 2, Badejọ Street, Agege, Lagos State.

## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imole Owuro)
N4/496B Yemetu Aladorin,
Ibadan:

# ATIORO ỌMỌ ATIALA

## A! Eniyan (1)

" A ! Eniyan" ni
Nasia t'o kan
Ti a fẹ ṣo
Fun ọmọ duniyan,
Oun na n'iwa ika
Ti nbẹ l'odo ikun rẹ,
Ti o nṣ'aiye l'ọṣẹ
Ti o fi njaiye l'ogun,
Ti o fi s'ọpọ eniyan di
Ẹni ti ko j'eeyan.
Iwa na pọ kari
Laarin ọmọ Adarihunrun,
O tilẹ wa papọju
Laarin Adulawọ eniyan.
A sọ pe, baba wa gbọn,
Ara wa l'a fi nṣe l'oṣẹ
A sọ pe nwọn n'imọ,
Eniyan ni nwọn nfi
Imọ demọlẹ;
Ani nwọn gbọn bi Eebo,
Ọgbọn ti nwọn gbọn
Ni nwọn fi nja
Ara wọn l'ogun;
Ani, nwọn lagbara,
Ani, nwọn le ja,
Ara wọn
Ni nwọn fi ntẹmọlẹ;
Nwọn a ko ọfa,




Nwọn a ko akatanpo,
Nwọn a ko
Ibọn t'o l'egboro;
Nwọn a ko kumọ,
Nwọn a ko ponpo,
Nwọn a maa fi le
Ọmọ eniyan ka lẹ
Lai ṣ'ọmọ ẹranko !
Oju mi ri gbogbo janmaa,
Mo ri nkan ara to
Gbogbo janmaa wa;
Mo ri nkan ara to
Laarin ọmo eniyan.
En yan ko ni'aari;
Eniyan ko nilaari jare,
Gbogbo ẹlẹgbẹ wa,
Eniyan ko nilaari
Eniyan ko sunwọn.
Bi ẹ ba r'eniyan l'Oke odo
T'o rogẹgẹ,
T'o fagẹgẹ
T'o nsọ pe,
Ko s'iru ohun
Ninu ẹni rere!
Ẹ ẹ gbo,
Ẹ ma da a lohu., ojare
Gbogbo ẹlẹgbẹ wa.
Bi ẹ r'ẹni t'o wọṣọ
T'o ṣe bi Ọba,
Bi ẹ r'eeyan
T'o ṣe gbẹdẹgbẹdẹ
Bi awọn Ijoye;
B'o nbọ l'okeere
Ti gbogbo janmaa
Nwolẹ fun un bi Ọba,
Bi nwọn ntẹgẹle aran;
Ti nwọn nki i pẹlu ọwọ;
B'oun na nrẹrin
T'o nṣ'adura fun wọn
Pe, k'aiye o dara fun wọn;
Ẹ ma gba a gbọ o,
Ki i ṣ'eeyan rere;
Adura ti nṣe ko denu,
Nṣe l'o ntan awọn eniyan !

Ani, ẹda buru,
Ẹda ko ṣeun,
Ẹda ko ṣ'eeyan rara,
Ọpọ wọn ko wulo !
Ki l'a a ti ṣ'eeyan si
Ki l'a a ti ṣọrọ
Awọn adarihunrun
A ! ọrọ ẹda su mi,
Eniyan ko sunwọn !
Mo wo rere aiye
Ng ko r'ẹni t'o buru
Bi ọmọ araiye !
Mo wo jinnajinna
Ng ko r'ẹni t'o ṣ'eeyan
Ninu ọmọ Adamọ duka!
Mo wọtunwosi,
Mo w'ẹni ti nbẹ
Ni sakaani mi
Pe, bọya mo le ri
Ẹni t'o nilaari
Ninu aiye gbogbo !
A ! Aṣe, bakanna ni
Gbogbo eniyan !

Mo wa ronu titi
Pe, bawo l'o ti jẹ
T'ẹda ko fi nilaari ?
Mo ro o jinna pẹlu
Bọya mo le mọ idi
T'eeyan fi burẹwa n'iwa;
Mo ro o titi,
Mo ri i pe,
Ẹda ti tapa s'Ẹlẹda;
L'ọrọ wọn ṣe nlọ lẹkọrọ-lẹkọro
Ẹda ti dalẹ iṣẹda,
Ẹda ti gbagbe ipilẹ;
Mo ri i pe,
Ẹda ti ṣọtẹ s'Ẹlẹda
Ni iwa ẹda ṣe bajẹ
Ti nwọn d'eleṣu
Lẹhin araa wọn;
Eyi l'ohunfa
T'o mu k'ẹda burẹwa
Ninu iwa.
Eyi ni nkan pataki
Ti Nasia wa yi
Yio duro le lori;

Mo si fẹ ki e gba
Bi a o ṣe maa ba
Nasia na lọ pe,
Eniyan buru,
Eniyan ṣoro,
Eniyan ko nilari,
Eniyan ko sunwọn
A ! Eniyan, Eniyan !

ỌLỌLA ATIOR

# 'SANJENTI SOJA F'ADA SA omo iya re pa'

Awọn Ọlọpa Ọtẹlẹmuyẹ ilu Abẹokuta ni Ipinlẹ Ọyọ ti bẹrẹ si i wa ọkunrin kan ti nwọn pe ni Ṣajẹnti Ṣọja kiri bayi l'ori ẹsun pe o fi ada ṣa ọmọ iya rẹ pa sinu ile.

Irohin lati ilu na ṣalaye pe, ni ipari ọsẹ ti o koja yi ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ati pe lẹṣẹkẹṣẹ ti ọdaran na daran na tan ni o na papa bora.

Gẹgẹ bi irohin ti wi, ọkunrin kan ti nwọn npe ni Ayinde Ṣokunbi ni nwọn sọ pe o padanu ẹmi rẹ ninu iṣẹlẹ na; ẹni ọdun mẹtadinlogoji ni i ṣe pẹlu.

Siwaju si i, irohin fi ye wa pe ni Ibadan ni Ṣajẹnti Ṣọja na ti nṣiṣẹ ati pe ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu kinni ọdun yi ni o lọ si Abẹokuta pẹlu ọmọbinrin kan ti awọn pe ni ale rẹ ti o si de si ọdọ ẹgbọn rẹ na ki o to di pe ọrọ na jasi iku fun Oloogbe na.

Bayi, awọn Ọtẹlẹmuyẹ ti nfimu finlẹ kaakiri l'ori ọrọ na sugbọn titi di akoko ti a gbe iwe wa lọ sori ountẹ, a ko ti i gbọ pe awọn Ọtẹlẹmuyẹ ri Ṣajẹnti na mu.

38

47

## Ilu mejila sorire ni Ondo

AWỌN ilu mejila ni o ti bẹrẹ si i tan ina Lẹntiriki bayi ni Ipinlẹ Ondo ninu eto anfani ina Lẹntiri ti ile iṣẹ NEPA nṣe kaakiri bayi.

Awọn ilu ti anfani na ti tẹ lowọ ni: Osi, Awọ, Ido Fabọrọ, Iropora, Usi, Igbie, Ijero, Aaye ati Ifaki ti gbogbo rẹ wa ni agbegbe Ekiti.

Awọn yoku ni Ilutitun ati Ode-Irele ni agbegbe Okitipupa.

Ẹni ti o sọ eyi di mimọ ni Akede ile iṣẹ NEPA fun Ipinlẹ Ondo, Ọyọ ati Ogun, Ọgbẹni Ọlaniyi Adeniji ninu ikede kan ti o gbejade.

Ọgbẹni Adeniji ṣipaya pe, ile iṣẹ oun ti pari iṣẹ l'ori waya titun lati Akurẹ lọ si Okitipupa, eyi ti yio mu ki ina maa tan daadaa ni agbegbe na.



ỌGAGUN D. IKPẸMẸ
Gomina Ondo


# AIYEDETISOLA COMMERCIAL, ELECTRONICS STORES

FOR YOUR:

Air conditioners, Generating Plants, Amplifiers, Public Address Equipments, 3&4 In One Stereos-System, Radio Cassettes, Tape Recorders, Car Cassettes, Radio Car Cartridge, Car Cartridge, Table Transistor & Pocket Radios; Stand, Table, Wall&Ceiling Fans; Deck Cassettes & Cartridge Eletric Kettles; Iron; Emmerssion Water Heaters; Cookers; Car eriels; Empty Cassettes; Batteries; Bulbs; Cable Wire, Electrical Accessories; Flourescent, Bowl & Ceiling Fittings, Welding Electrodes; Kerosene Stoves and Cooking Utensils etc. etc.

Please, visit our showroom

BLOCK AN41 I. C. C. STALLS,
AGODI MOTOR PARK,
IBADAN,

# Ẹgbọ t'emi

## Nasia Atioro dara pupo

OLOOTU,

BI a ko ba ni i pẹgan, Ọlọla Atioro nṣe Nasia gidi. Nasia rẹ kọ ni lọgbọn, o ki ni nilọ o si ngba ni n'imọran lori ọna igbesi aiye ẹni gbogbo.

Mo fẹran lati maa ka Nasia Atioro pupọ, mo si ti ri i pe ẹnikẹni ti o ba ntẹle imọran Ọlọla Atioro ko ni i kabamọ ninu aiye rẹ. Ẹgan ni "Hẹ", Nasia Atioro dara pupọ.

Emi ni,
Iṣọla Adegbindin,
Ile-Ọgọ,
Iwo.

## E maa da won s'ewon

OLOOTU,

O dara gẹgẹ bi Ijọba Apapọ ṣe fi agbara kun agbara awọn oṣiṣẹ Adiyelọja lati maa ju ẹnikẹni ti o ba ko ọja pamọ si ẹwọn lai ni owo itajẹ.

O dara bẹ gan-an ni. Ẹwọn ni ki ẹ maa da wọn si. Nigba ti nwọn ba nju wọn si ẹwọn, nwọn yio jawọ nibẹ, awọn yoku yio si fi tiwọn kọgbọn.

Emi ni,
Tiamiyu Adeẹyọ,
Eko.

## Ofin na dara sugbon.....

OLOOTU,

MO faramọ ofin ẹwọn ti Ijọba Apapọ kede pe awọn Adiyelọja yio maa lo fun awọn elere ajẹju ati awọn ti nko ọja pamọ.

Ṣugbọn mo fẹ ki Ijọba tojubọ awọn alagbata tabi olupinja (Dealers &distributors) nitori awọn gan-an ni o wa nidi iwa buburu na.

Awọn l'o nba Naijiria jẹ, awọn ni ọta mẹkunnu, awọn l'o njẹ ki ara ni ilẹ wa.

Ẹ ba ni fi ofin ẹwọn da wọn l'ẹkun.

Emi ni,
Adisa Adeẹyọ
Ẹpẹ

# 35

## E gba wa o

OLOOTU,

MO nfi iwe mi yi kesi Ijọba Ologun lati gba wa kalẹ lọwọ awọn Ọlọṣa ti o nyọ wa l'ẹnu ni agbegbe Odo-Ọṣun.

Lai pẹ yi ni awọn Ọlọṣa kọlu awọn aba mẹrin kan: Aba Oyekunle, Alagutan, Ali ati Balogun Mini.

Nṣe ni awọn Ọlọṣa na kẹlu olugbe aba wọnyi, ti nwọn pa wọn lara ti nwọn si ko dukia wọn lọ.

A dupẹ pe awọn Ọlọpa Ijẹbu-Igbo ti ko awọn enia kan ti nwọn fura si l'ori ọrọ na.

Ṣugbọn a bẹ Ijọba Ologun ki o pese aabo fun agbegbe na o.

Emi ni,
Raimi Adeṣokan,
Aba Oyekunle,
Oke—Ọṣun
Lẹba Ijẹbu-Igbo.

ADIRẸSI OLOOTU

OLOOTU,
IMOLẸ OWURO,
P.M.B. 5230,
IBADAN


# A ṢE E KI O LE MAA LỌ RE MAA BỌ RE




**Suzuki B120**

Enjinni B.120 alagbara (9.8 horsepower) l'a gbe s'ara t'o fuyẹ sugbọn t'o lagbara.
Pẹlu agunki nla (shock-absorbers) lati le rin gbogbo ọna, laisi iyọnu fun ọ! Ina nla alagbara niwaju ati lẹhin -- ki o le maa riran falala, laisi ewu. Bireeki (idakoro) ti kii ba a ti l'ojo l'ẹẹrun. O dara ki o ni alupupu Suzuki ti a pilẹ ṣe nitori ti'ẹ.

SUZUKI Alupupu alalọbọ



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

# Akédé ọ̀na Iyè

ONAKANSOSO SI IYE AINIPEKUN

# Okunrin ti o ba ri aya rere fe (2)

"MO si ri ohun ti o koro ju iku lọ. Ani obinrin ti aiya rẹ i ṣe idẹkun ati awọn, ati ọwọ rẹ bi ọbara. Ẹnikẹni ti inu Ọlọrun dun si yio bọ lọwọ rẹ, ṣugbọn ẹlẹṣẹ ni a o ti ọwọ rẹ mu." Oniwaasu 7; 26.

Ni ọse ti o koja ni a sọ nini Apa kinni iwaasu yi pe, Ọkunri ti o ri aya rere fẹ ba ojurere Ọlọrun pade. A sọ nipa oniruuru iwa ati iṣe ọpọ ọkunrin ati obinrin ninu aiye, eyi ti o nmu ki igbesi aiye ọkọ ati aya dara tabi buru. Pẹtẹpẹtẹ ni ọrọ na ti a sọ, bi o ṣo ntaba ọkunrin ni o ntaba obinrin.

Awọn ọmọ enia a maa fi ọpọ igba parọ mọ kadara tabi da ẹbi fun kadara nigba ti nwọn ba fi ọwọ ara wọn fa ibi ba ara wọn tan; ṣugbọn mo nilati sọ fun olukuluku enia l'oni yi pe gedegbe ni kadara wa, l'ori otitọ ati ododo ni o si nṣiṣẹ.

Ṣugbọn nigba ti iwa aiṣotitọ ati aiṣododo wa ba bi ẹṣẹ, ẹṣẹ na a si ti wa lati yapa kuro ni ọna ti aiye wa le gba dara. Ẹjọ kadara wa kọ ni eyi, awa ni a fa a.

Ọpo ọkunrin l'o ti fi aya rere ti ki ba fẹ ninu aiye ṣe ale ti nwọn si nfi eyi ti ki i ṣe aya wọn ṣe aya. Bakanna ni ọpọ obinrin ti fi ọkọ rere ti ki ba fẹ ninu aiye ṣe ale ti nwọn si nfi eyi ti ki i ṣe ọkọ wọn ṣe ọkọ wọn. Nitori idi eyi, ibagbepọ wọn gẹgẹ bi ọkọ ati aya jasi ibanujẹ.

Melo l'a o ka ninu obinrin ti o yẹ lati kọju si ẹkọ wọn ṣugbọn ti o jẹ pe, okunrin ni nwọn nwa kiri? Bi o ṣe pe aburo ni kadara wọn fẹ, nwon a fi i ṣe ale. Bi nwọn ba jade ile ẹkọ tan ti nwọn lọ silu Oyinbo ti nwọn si ba ẹgbọn pade, nwon a fẹ ẹ ṣe ọko. Eyi ti nwọn ṣe yi ti lodi si kadara wọn.

Nigba ti nwọn ba ṣe igbeyawo tan ti nwọn

Ọpọ iru obinrin bẹ ni nwọn maa nfi ile ọkọ ṣe ile ale ti nwọn si maa nṣe iku pa ọkọ wọn.

Melo l'a o ka ninu ọkunrin ti yio maa ba iya ṣe ale ti yio si tun fi ọmọ rẹ ṣe aya! Njẹ inu Ọlorun le dun mọ iwa bi iru eyi?

Nigba ti ile iru ẹmi bẹ ba bẹrẹ si i daru, ọmọ araiye a wa bẹrẹ si i fi

nile, ki o kalọ si ile ọrẹ oun lati lọ ba ọ lopọ nibẹ; o ti yẹ ki o mọ ni ọkan ara rẹ pe, iwọ ko tii ni ọkọ. Tabi nigbati oyun ba de inu rẹ ni iwọ yio to mọ ile ọkọ ti o nfẹ? Ṣe nigbana ni o to yẹ ki o mọ enia rẹ, ati iyawo rẹ, ati ọmọ rẹ?

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

pada dele, aburo ti o ti nba sale tele ati ẹgbọn ti o fi i ṣe iyawo a pade pọ, nwon a di meji l'ori oun nikan. Bi aburo ba gori rẹ l'aaro, ẹgbọn ti o jẹ oko yio gori rẹ l'alẹ! Bawo ni iru ile bẹ ṣe le toro?

ẹnu wọn dajọ eke. A! ẹnyin ọmọ enia, ẹ nhuwa aito, ẹ ni Ọlọrun ki i binu! Ara nyin l'ẹ ntanjẹ o. Bawo ni Ọlọrun ki i ṣe e binu? Iwọ ro pe inu Ọlọrun a maa dun si iṣẹ buburu bi? Jẹ ki o ye olukuluku enia ti nka iwaasu yi pe, gbogbo iwa ti o yapa si ifẹ Ọlọrun pata ninu aiye yi ni o nfa ibinu Ọlọrun; nitorina, ẹ sa fun iwa ti o le fa ibinu Ọlọrun.

Ọkọ rere ati aya rere l'o maa nbi ọmọ rere, ile wọn si ni ile rere. Bibeli wi pe, "Obinrin Oniwarere li ade ọkọ rẹ, Owe 12; 4. O tun sọ pe, "Enia rere fi ogun silẹ fun awọn ọmọ-ọmọ rẹ;' Owe 13; 22.

Njẹ iwọ ọkunrin ti o fẹ aya buburu, kinni iwọ yio ha fisilẹ fun awọn ọmọ rẹ? Ati iwọ ọmọbinrin ti o fẹ janwee ọkunrin ni ọkọ, ti ẹ nfi tọsantoru jojo ẹlẹya kiri ti ẹ ko si gbe igbesi aiye rere, nibo l'o fẹ ki igbesi aiye rẹ pari si, ogun wo l'o si fẹ fisilẹ de ọmọ?

Iwọ ọdọmọbinrin ti ọkunrin nsọ fun o pe, iyawo ati ọmọ oun wa

Bayi ni ọpọ ọmọbinrin ti fi iwakiwa-ani, aitete sunmọ Ọlọrun ati aitẹle ifẹ Ọlọrun, ṣi ara wọn l'ọna ninu aiye; idi si niyi ti ọpọ ile lọkọlaya fi daru l'ode oni.

Eyi ti o tilẹ buruju ni ti ọkunrin ti o mu aya rẹ lọ si ile Ọlọrun, ti o fi ẹnu ara rẹ bura pe, lailai, oun ki yio ya kuro ninu ifẹ Ọlọrun ṣugbọn ti o wa jẹ pe, ounjẹ aṣẹwo l'o tun wa dun l'ẹnu rẹ ju ti iyawo titun lọ.

Nitorina iwọ ọmọ enia ki o to l'aya tabi ki o to l'ọkọ, ilana Ọlọrun ni ki o tẹle ki o le dara fun ọ. Bi a ba si ti yan aya rere fun ọ tan, ti o ti ba ojurere Ọlọrun pade, ma ṣe tẹle ipa ẹṣẹ ki o ma ba ba ile ara rẹ jẹ nitoripe; "Ẹni ti o ri aya fẹ ri oju rere Ọlọrun".

Kunlẹ Adura,

ADURA

Oluwa, Ọrọ Rẹ ni mo gbọ yi. Iwọ ni Ọlọrun Ọrọ ati Iye. Aworan Rẹ ni emi i ṣe. Atunṣe aiye mi si rere nbẹ lọwọ rẹ. Jọwọ ma ṣai wa tun aiye mi ṣe ki ng le ba aanu Rẹ pade lati ni aya rere. Ki ọrọ mi ma ṣe la abamọ lọ lati isinsinyi lọ ati titi lailai, Aamin.

# Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

- 12,419 Oluṣegun Jẹgẹdẹ, Eruwa
- 12,420 Samuel Ogunmileto, Ikeji-Arakeji
- 12,421 Adeniyi Oyeyimka, Ọdẹ—Omu
- 12,422 Hasani Iṣọla Ilorin
- 12,423 Amos Ọlaoye, Gbọngan
- 12,424 Kẹhinde Adegboyega, Abẹokuta
- 12,425 Musa Aiyenfaajo, Ibadan
- 12,426 Rasaki Belo, Apomu
- 12,427 Mukaila Jimọ, Ibadan
- 12,428 Ramọta Ọlatubọsun, Abẹo—kuta
- 12,429 B. A. Ọlatubọsun, Abẹokuta
- 12,430 Sule Adeṣina, Ibadan

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe I[illegible]i Ọmo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ ______________

Adirẹsi rẹ ______________

Ọmo ilu ti o jẹ ______________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(A[illegible]ẹ)
P.M.B. 5230, Ibadan

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (42)

Lawuyi Ogunniran
Ọọku l'oni o, Alajao mi,
Ajao Alayọ ọmọ baba Lasun.
Iyawo rẹ nkọ.
Ṣe nbẹ l'alaafia ara?
Okele ko ni i ha ọ l'ọrun,
Ata ko ni i pa ọ l'ori.
Kafilatu ae nkọ,
Ṣe nbẹ l'alaafia ara ?

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
O ṣehun l'aiye ọmọ Ejigbọjọ
Awọn ara ilẹ a tun tirẹ ṣe,
Oo ya, o o ra, o o ni i tẹ;
Agbara l'ọwọ Yarabi
Ti i j'Ọlọrun Ọba;
Edumare ko ni i jẹ ki
Gbogbo ohun t'o nro o ja buẹbuẹ.
Iyawo rẹ nkọ, ọmọ Ejigbọjọ
Ara ọmọ le tabi ko le ?

Lawuyi Ogunniran
Ajao! Maa gbọ ọmọ Ajiṣegiri,
O yẹ ki o ki mi titi
Ki o si dupẹ lọwọ mi gidi
Ti mo kilọ fun ọ l'ori ibo
Ti o so pe o fẹ di tẹlẹ.
Ṣe o ti ranti pe,
O so pe o fẹ d'ẹni nla?
O si so p'ọna iṣelu
L'o fi fẹ da bẹẹ,
O ni o o dibo wo,
O ni b'aaye ba ṣi,
O fẹ d'Olori Ijọba t'o tobi
Nitori o fẹ lokiki
O si fẹ j'eeyan atata ?
Ṣe o wa ri ohun
T'oju ẹni ti ndibo ri ?
Ṣe o r'atata iya
Ti njẹ Kansilọ t'o kuna ?
Ṣe o ri_______ ?

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ki l'o fẹ maa wi ọmọ Ejigbọjọ ?
Boya o fẹ sọ pe
Bi mo ba dibo ọhun
Pe, ng ko ni i moke ?
Bi o ba nro ifu eyi,
Yẹyẹ ta ọ t'ina
Nitori o da mi loju pe,
Enia t'o ba doju kọ mi
Ki ba ti r'owo idogo gba.
Nitori lati ọjọ ti mo ti d'aiye
Ng ko ṣ'ẹnikan nibi;
Ng ko da ọmọ oku l'oro,
Ng ko ṣika ọmọ orukan;
Ng ko jale, ng ko kowo na
Ng ko ṣe buburu,
Ng ko hu ẹnikan nibi;
Gbogbo enia l'o si ndun pe
Ng ko kọ..tẹẹsi;
Nwọn ni, bi mo ba Kọntẹẹsi,
Awọn ki ba dibo pelemọ fun ni.
Nitori emi l'awọn nfẹ
Ki ng ṣ'oju wọn n'Ipade Igbimọ.
Iwọ gan-an l'ọdada,
Iwo l'enia t'o da gbogbo rẹ silẹ'
Iwo l'ọrẹ alugan-nbi
T'o di mi l'ona
Ti ko jẹ ng ṣ'oju adugbo wa
Boya ng ki ba d'Alaga Igbimo
Fun gbogbo Kansilo ninu Igbimo
Ṣugbon mo ti wa ri i pe,
Ẹmi ni a ri ba wi
Ti mo tara gbo 'hun too wi,
Emi ni a ba soro si
Pe, mo jẹ ki o ṣi mi l'ona
Emi ni mo tete gba o gbo
Ti mo tẹle oro rẹ gbogbo
Ti ng ko mo pe,
Imoran eṣubeleke
L'o ngba mi l'ori oro.
A ! Aṣe bayi l'aye ri !
Aṣe bayi l'eeyan ri gbogbo janmaa!
Eniyan ti aa gbẹkẹle
Ti a mu bi olutọna,
Ẹni ti a gbarale
Bi ẹni t'o yẹ ko ran ni lọwọ
Bi a ba fẹ d'ẹni giga;
Eniyan ti a pe s'ọrẹ
Pe, ko fun ni n'imọran
L'ori oro pataki,
T'o wa nf'ogbon alumokoyi
T'o fi mu ni kuro l'ona ibi a fẹ lọ;
Taa ni ko ṣai mo pe,
Iru won ko ṣai J'oṣika eniyan!
Aṣe, ibo t'o nkilo lelori
Ki i ṣe ibo t'o buru,
Aṣe ibo t'o ni ki ng ma di
Ki i ṣe ti wahala;
Aṣe nijo a ti ndibo nilẹ yi
Ko s'eyi t'o dara
T'o si l'ere owo goboi
Ko s'eyi t'o niyi t'o tobẹẹ ninu ibo.
Ibo t'eniyan di tan
T' Ijoba nfun ni lowo !
Kasilo yio gb' Ọgorun loṣu
Alaga t'Ibadan yio gba
Naira t'o le l'ẹgbẹta (₦666.00)
Amugbalẹgbẹ rẹ yio gba ẹgbẹrin (₦400.00)
Ohun t'orẹ mi fi ṣe mi ree gbogbo janmaa!
Bi mo ba j' Alaga Ibadan
Ẹ wo 'hun ti nba maa ri!
B'o ṣe Amugbalẹgbẹ,
Ẹ wo Naira-Naira!
B'o tilẹ jẹ Kansilọ lasan
Ẹ wo 'ye ti ng ki ba gba
B'oṣu ba ti nd'opin!
Gbogbo re l'Ayinde gba junu
Nitori oun l'o ṣeru ba mi
Ti ko jẹ ng di Kansilo tẹlẹ
A ! Aiye buru! Enia ko sunwon !

---

Haco Nap

3
14
30

3 5 10
9 12 26

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ, RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba N10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati itumọ (₦1)
5. Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦5); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni ala (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)
FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:
(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.

(2) Alufa Igbaẹlode, Mọsalasi Idi-Işin St, Isalẹ Koto P. O. Box. 17 Ilorin

# KI L'O ṢẸLẸ?

## Iyawo Oloti ta oti daran

ILE – ẸJỌ ti nṣejọ awọn ti a ba fi ẹsun ere ajẹju ati kiko oja pamọ kan, ti ju obinrin onile itura kan, Amẹlia Ọjẹṣoba si ẹwọn oṣu mejila tabi ki o lọ san ẹgbẹrun Naira (₦1,000.00) si apo Ijọba gẹgẹ bi owo itanran.

Ẹsun ti awọn afẹsunkanni fi kan obinrin na ni pe, o paṣẹ fun oṣiṣẹ rẹ kan, Agboola Hassan lati ta ọti Bia Top ni Kobọ marundinlaadọrin (65k) igo kan dipo kobọ marundinlogọta (55k) ti Igbimọ Adiyelọja palaṣẹ.

Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kinni ọdun yi ni nwọn sọ pe nwọn daran na nile itura ti njẹ Shepherd Hotel nilu Ilọrin.

Ninu ọrọ rẹ, obinrin na sọ pe, ọkọ oun l'o ni ile ọti na ati pe, oun kọ ni o fun oṣiṣẹ ti o ta ọti na ni aṣẹ lati ṣe bẹẹ.

Ninu idajọ rẹ, Adajọ ile ẹjọ na, Ọlọla Timothy Oyeyipo sọ pe, opurọ enia ni obinrin na i ṣe, o si paṣẹ ki o lọ san ẹgbẹrun Naira owo itanran tabi ki o lọ fi ẹwọn oṣu mejila jura.

Adajọ na kilo pe, ki olukuluku lọ fi opin si ere ajẹju tabi kiko oja pamọ nitori ẹnikẹni ti o ba jẹbi ẹsun na niwaju oun, yio jiya tan, yio tun jewe iya.

25 & 29

## Gomina Oyo yo Adajo n'ise

IJỌBA Ipinlẹ Ọyọ ti yọ adajọ ibilẹ kan n'Ilu Ibadan, *Oloye* Lasisi Ọladejọ Ọlaoye ti iṣẹ Lagunna Olubadan Ibadan ati amugbalẹgbẹ rẹ kan, Alhaji Tiamiyu Asani Balogun niṣẹ bi ẹni yọ jiga fun jijẹbi ẹsun gbigba riba l'ẹnu iṣẹ.

Ikede kan ti o jade lati ile iṣẹ Eto Ijọba Ibilẹ nilu Ibadan sọ pe ile ẹjọ Ibilẹ Onipo Kẹta nilu Ibadan ni awọn enia na ti ndajọ.

Ikede na sọ pe Gomina Ologun Ipinlẹ Ọyọ, Ọgagun David Jẹmibẹwọn ti f'aṣẹ si yiyọ ti a yọ awọn enia na n'iṣẹ.

Ikede na ṣalaye pe awọn enia mejeeji na jẹbi ẹsun riba gbigba ati iwakiwa l'ẹnu iṣẹ, eyi ti ko yẹ iru awọn enia ti o ba wa ni iru ipo bẹẹ.

Gẹgẹ bi ikede na ti wi, ọpọlọpọ ẹsun ni awọn enia ti fi kan wọn ki o to wa di pe Ijọba ṣe iwadi ẹsun wọnyi ti nwọn si ba a bẹẹ pe, nwọn jẹbi.

27

46


## ADEDEWE FUN TITA

EYI ni lati sọ fun gbogbo enia ti o ti nbeere iwe ADEDẸWẸ ti Ọgbẹni Lawuyi Ogunniran kọ pe a ti ni fun tita bayi.

Gẹgẹ bi ẹyin na ti mọ, iwe na kọ ni logbọn pupo o si yẹ ki olukuluku enia ni lọwọ ati ọmọde ati agba, paapaa o dara lati fi tọ ọmọ ẹni sọna.

50k ni ẹyọkan, fi owo oniyekiye ti o ba fẹ ra ṣọwọ si:

Alufaa Yisa Igbaelode,
N2/394A Odoye,
Adeoyọ Road,
Box 3365,
Ibadan.



## NIGERIA NEW STATES CO.

jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe: Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lọ, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



## KEREO

GBOGBO - ENIA!

*fun*

*•Ipolowo ọja ati Ikede,*
*•Akiyesi ati Itufọ,*
*•Iranti oku ati Ikede Ariya,*
*•Ikilọ ati bẹbẹ lọ;*
*•Tabi Almanak ati Kalẹnda titẹ.*

DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI ONṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ, SA KỌWE TABI KI O WA RI:-

*Advertisement Manager:*

IMỌLẸ OWURỌ
N4/496B YEMETU ALADỌRIN.
P.M.B. 5230, IBADAN.

# Agbéyẹ̀wò ohun titun t'o gbòde

REKỌDU, IWE, ORIN, ARE-IDARAYA.

# MISITURA ADUKE GBE TITUN DE

BI ẹnyin onkawe wa kò ba gbagbe ninu oṣu kejila ọdun ti o kọja ni oju ewe Imọlẹ Owurọ yi, ni a to tẹ irohin kan jade pe, gbajumọ Obinrin alare Dundun ati Ṣẹkẹrẹ nni, Misitura Adukẹ ti ṣe awo rẹkọdu Keji eyi ti a sọ nigbana pe yio jade ninu ibẹrẹ ọdun titun fun igbadun asiko isimi ọdun na.



MISITURA ADUKE
Ati Oniyaalu Rẹ

Ṣugbọn riro ni ti enia siṣe ni ti Oluwa. Gẹgẹbi a ti gbọ l'ẹnu Ile Iṣẹ OGO OLUWA RECORDS ni asiko na ni a fi to yin leti, eyi ti ko bọ si i bi awọn na ti l'ero nitori idiwọ diẹ ti nwọn ni lati odo awọn ti o ntẹ awo na fun wọn.

Ṣugbọn awo na ti wa jade fun tita bayi.

Awo ti a nwi yi, Arabinrin Misitura Adukẹ Ayantunji ati awọn alare Dundun ati Ṣẹkẹrẹ dan nkan wo sinu awo na.

Ninu ohun ti nwọn fi kọrin ninu awo na ni orin Egungun Oloolu ati nipa ọwọn Ounjẹ.

Arabinrin Misitura sọ bi gbogbo nkan ti wọn si l'ọja ti o fi di pe ati jẹun di ọran, Nitori eyi, o wa kesi gbogbo enia lati gbaruku ti Ijọba Apapọ nipa eto "Kebi ma pa ni" ti nwọn gbekalẹ fun anfani temitirẹ.

Bi orin ti nlọ bẹẹ na ni Dundun ati ṣẹkẹrẹ ndun letoleto ti o fi dun i jo. Awon owe ati Ijinlẹ oro, ti o ko ni logbon ni onilu na nfi janasi si orin na; paa- paa enia yio tun maa ri awọn owe na lo ninu ti a ba nsọ.



ỌGBẸNI J. O. AFỌLABI
Alakoso Ogo Oluwa Records

Awo na ti nonba rẹ jẹ OKLP 67 koyoyo, inu awo na ti o fi jẹ pe ati alakowe ati eniti ko mọ iwe na ni yio gbadura awo na, paa- paa yio tubo jẹ ki gbogbo araiye ni ife si are Dundun ati ṣẹkẹrẹ.

Ninu awo na, o ki awọn enia ati ẹlẹgbẹjẹgbẹ ti o ki ni ona ti o ba oju mu ti ori ẹni ti o ki na yio fi wu.

## Rekoodu Layigbade di Goolu

IROHIN ti o de si ile-iṣẹ wa lati ilu Eko, Ẹpẹ Ikorodu ati agbegbe rẹ, fi ye wa pe awo titun ti gbajumọ alare Sakara asiko nni n'ilu Eko, Saka Adio Layigbade ti di goolu bayi ti awọn enia nwa awo na kiri lati ra ni iyekiye.

Onirohin wa ti o lọ kaakiri awọn ilu wọnyi fi ye wa pe, ojoojumọ lati bi ọsẹ mẹta sẹhin ni awọn enia ti nbeere rẹkoodu na, ti o fi di pe, rẹkoodu Naira mẹfa di Naira mẹjo! Sibẹ awon enia ko kọ lati ra a ni Naira mẹsan, bi nwọn ṣe ni ifẹ si awo Layigbade na to.

Nigba ti onirohin wa lo si Ọdọ Ọga Agba Ile-Iṣẹ Adetunji Ọmọ Aje Sound Studio ti o - ntẹ awo na jade, Alhaji Ambali Adetunji, lati lo beere nipa ohun ti o fa a ti awon enia fi ndu awo na ra bẹẹ, Alhaji Adetunji fi ye wa pe, iyalẹnu ni o jẹ fun awon paapaa nigba ti awon Onibara ṣuru bo awo na, o si ti di igba mẹfa ti awọn yio tẹ awo na si ilẹhin ti akọkọ jade, eyi ti o ti nlo bi ẹgbẹrun marun bayi. O ni, bayi, awon ti tun beere fun ẹgbẹrun kan si i nitori ki awon le tẹ awon olufẹ ere na lọrun.



SAKA LAYIGBADE
Awo rẹ di Goolu

# Ijoba wole Ogboni

NWỌN ti wo ile Ipade Ẹgbẹ Ogboni ilu Owerri lulẹ nipa aṣẹ Gomina Ipilẹ Imo, Ọgagun Ndubuisi Kanu.

Bakanna ni nwon wo awon ile miran lulẹ ninu ilu na l'abẹ aṣẹ kanna.

Ohun ti Ijọba so pe o fa a ti awon fi wo awon ile na ni pe, nwon ndi eto ilosiwaju ilu lowo.

Irohin fi ye wa pe nigba ti awon enia ti oran na kan nkun kaakiri ni ikede Ijoba jade pe ki nwon lo joko jẹẹ.

Ikede Ijọba sọ pe ile ti awọn yio tun wo ku ati pe, Ijọba ti nkilọ fun awọn ti o ni awọn ile na tẹlẹ lati kojade nibẹ ṣugbọn ti nwọn ko gbọ.

# POOLS!

**Top Three**

# 8
# 20
# 16

# 30
# 40
# 46
# 48



MU ORIRE TIRẸ NINU AWORAN YI

**12 22 36 37**


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI A JẸ ONIṢOWO TI O DARA
NI O NKESI ẸNYIN ONIṢOWO GẸDU
PE, A TI GBE ORIRE TIYIN NA DE:
BI Ẹ BA NFẸ KI IṢẸ NYIN MAA
GBERU SI I,
TI Ẹ NFẸ KI OWO NLA-NLA MAA WỌLE
TI Ẹ SI FẸ WA NI YỌTỌMI
NI GBOGBO IGBA,
ẸRỌ WA ATATA ALAGBARA
NLA KAN TI NJẸ




## Solo Chain Saw

## 30" Bar (N350.00)

Ti a fi nge gẹdu ni orişirişi
Ni o yẹ fun ọ lati ra.
Bi o ba ti ni ẹrọ na
Ma foiya mọ, bukata rẹ ti biiya.
Owo ẹrọ na ko pọ, ₦350.00 pere ni.
Ki işe iru ẹrọ yi nikan ni a ni,
Orişirişi fun oniruuru işẹ ni o nbẹ pẹlu

Bakanna ni a si ni ẹrọ "BECO"
Ẹ sa tete maa bọ pẹlu Imọlẹ Owurọ ti a polowo ẹrọ yi si ninu wa si:

## Western Nigerian Technical Company Limited

WENTEC 1955

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/496B Yemetu Aladorin P. M. B. 5520, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, S4/983, Aremo Adekile Ibadan. Lagos Office: 14, Odunlami St. Phone 27817.